U. T. C.
DEPARTMENT STORE
SERVES
YOU
WELL

ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJO

## Akiyesi Pataki

A fiwe yi ṣ e ikede si awọn Aṣoju iwe irohin Eleti-Ọfẹ kakiri agbaiye wipe, ẹnkẹni ti ko ba f i owo ti o ti jẹ ranṣẹ si wa, a o pe lejọ, ako si ni f i iwe iroh in ranṣẹ si enibẹ mọ.

VOL. XI No. 635. LAGOS, SATURDAY, AUGUST 1 — AUGUST 7, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Lemomu Sonu, Won Nwa Bata Ladani, Oro Na So Koko!

**ILỌRIN** Rogbodiyan lori ọrọ Ijọba Ibilẹ Ilọrin ati ti ọba Ọffa koiti tan ni igboro Ilọrin. Lẹhin igbati ijọba Ariwa tu awọn igbimọ Ibilẹ Ilọrin ka tan ti wọn si yọ ọba ilu Ọffa kuro lori oye nitoripe ọjọ ori rẹ pọju ni atuugbọ wipe awọn Ijọba Ibilẹ Ilọrin bere si da awọn ọlọpa duro lẹnu iṣẹ.

Awọn ọlọpa merinla, Saji kan ati Kọburu mẹta ni awọn Alabojuto Ijọba ibilẹ da duro kuro lẹnu iṣẹ, nitoripe pupọ won lọ jẹ omo ilẹ Yoruba.

Pupo ninu awon ọlọpa ti a da duro yi ti mbẹ ninu iṣẹ fẹrẹ le ni ogun ọdun, ti nwọn sọ fun pe ki nwon bọ aṣọ silẹ.

A tilẹ gbo wipe, nigbati nwon soro yi ni agbala ọba awon Oyinbo olopa meji ti o wa ni ipade na ko fara mo. A tilẹ gbo pe Ọgbẹni Ọlawọyin ti ko iwe si Gomina klo da iwa nwonyi duro ni ilẹ Ilorin.

Nitoripe lori ao wa oba lo, ni a se tu Igbimo ka, ni ojowo ni if'okanbalẹ yio de ilu Ilorin ?

### OTITỌ NI YIO LEKE

Otito ki o pe, Oṣika ki o pẹ, ilẹ l'o mo ẹniti yio tẹ on pẹ.

### NWỌN FORUKỌ ỌMỌ ỌDUN MẸFA TA ORIRE

EKO Ọmọkunrin kan ti nwon npe ni Ọga-ọta, ta orire ti Irish nilu Oyinbo, ṣugbon ko fi oruko ara re ta orire na, orukọ ọmọ rẹ ti o sẹsẹ bi, ti ko ju omo odun mẹfa lọ ni o fi ta.

Ọmọ na si ṣe orire, o jẹ ẹdẹgbata Poun (£5,000), gbara ti o ri iwe gba, o kọri si Banki lati gba owo.

Nwon bere lọwo rẹ wipe, tani njẹ Baby-Ọta, o dahun pe ọmọ on lo njẹ be. Nwon ni k'o lọ gbe wa ki nwon ri. Nigbati nwon ri, nwon bere lowo Ọga-ọta wipe, ọmọ ọdun melo ni omo na ? O dahun pe, o di omo odun mẹfa.

Nigbana ni nwon wi fun Ọga-ọta pe ko ni ẹtọ lati gba owo na, sugbon awon yio toju owo na titi omo na yio fi dagba to odun mokanlelogun ki o to wa gba owo na funra rẹ.

Ọga-ọta fi owo mu ori wipe ye, ye, ye, aiye mi re, Kini nma t iṣe ?

### ỌKỌ OYINBO NLA TI O BAJẸ NPADA BỌ WA SILE

NEW YORK. Ọkọ Oyinbo kan ti nwon npe ni 'Queen Elizabeth' ti o ma nrin irin ajo lati ilẹ Gesi si America ti o si jẹ wipe on ni ọkọ ti o nko awon ero ni gbogbo aiye ni a gbo pe, o ṣe pẹkireki pẹlu ọkọ igbaja kan nwon si kọlu ara nwon ninu okun Atlantic. Nwon si tun ọkọ na ṣe nilẹ America.

Enia dudu kan, ara ilẹ Nigeria oniṣe ijoba ti o mba ọkọ yi lọ silẹ Amerika sọ pe, irin ajo on ko ni ṣeṣe mọ. On ni lati ba ọkọ Oyinbo nla yi pada lọ si London, lati ibẹ ni on yio ti ba oko ofurufu fo pada silu Eko, ki on ba le ba ipade igbimọ ti nwon fẹ ṣe ni ojọ Alaruba ti o mbọ yi, nitori igbimọ ti nwon fẹ ṣe yi ni aṣegbẹhin.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E.Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajẹla ọmọde agbọmola bi oriṣa, akọkọlukọ ogun ti ndamọ l'ẹkun igbona, atata ogun ti npa o tutu rẹ warawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abiu di ikugbagbe, o ṣ'ọmọ ti nhehin l'ore, Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aiperi ri d'ẹkun iyọnu Olugbala f'ọmọ ti nyagbẹ ọrin o kapa inu wọ, o lu jedi l'alupa gbogbo abiyamọ nyọ ṣẹṣẹ. Ela ri i o roju, Ọrerẹ ri i o na'gbẹ bo'ra Eyi npa lẹmọ lodilẹsọ, ọrẹ ikoko, koṣemani awọn abiyamọ, ẹni araiye njijadu ra. O de ilu Ibo, o dọga o de ilẹ Hausa, o d'ọba gbogbo Oniṣegun l'o so pe ko lẹgbẹ gbogbo ọmọde lo nfẹ ẹ fun ilera

IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4s owo ọkọ lọtọ.

THE EGBA TRADING
ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2 Ebute-Metta



## OLOPA RI OMOKAN GBA SILE LOWO AJOMOGBE

OVIM STATION. A gbo irohin wipe awon gbomogbomo ji omokunrin kekere kan gbe, ara Ilu Item lona Benda, lati Station kan ti nwon npe ni C ʃ π.

Nigbati nwon de i l u Aba, nwon so kale.

Sugbon nigbati nwon r i awon olopa Reluwe ti o mbo wa si apa odo won ni won ba fi omo nikan sile, ti nwon si salo.

Awon olopa se akiyesi omo na nibiti o gbe joko si ti o nromu, a w o n olopa sunmo nwon si bere ohun ti o se e.?

Omode na rohin fun awon olopa gegebi nwon ti ji on gbe ni Station Ovim, on ko ri eniti yio gba on sile lowo won on ko si mo ibi ti nwon ngbe on lo.

Agbo pe awon eni meji n a ti ba moto lo sibi lofi ara awon olopa nse ode awon ajomogbe meji na lowo.

## SARDAUNA SOKOTO NDAKAN BOWA SILE

KADUNA. A gbo w i p e Sardauna Sokoto pelu S a k i Oba Kano l o jijo mu faaji isimi olofe ara lo silu Oyinbo nwon fe de ile Faranse ile Jamani ati Oslo, nwon ko si ti pari akoko isinmi won nigbati nwon ri iwe gba wipe kiakia k i nwon mabo nile nitoripe lojo Alaruba 12th osu August ni nwon ma si igbimo Asofin (Assembly) ni Kaduna.

Nwon o fo pada si Faranse ni ojo Saturday 8th osu August 1959.

Bi nwon ba kuro nibe, nwon of o lo si ilu Venice nile Italy, ati lati ibe si Tripoli n i l e Afrika.

Bi nwon ba kuro nibe, o di ilu Kaduna lojo ti n w o n o se igbimo gan.

## Awon Alayewo Ofin De Ilu Oyinbo

**LONDON—Oloye F. R. A. Williams, Q. C, o jẹ ọkan ninu awọn ogbonkangi ninu ofin ile Nigeria ati ti Gẹsi ti nwọn yan lati lọ ṣe ayewo ofin ilu Oyinbo.**

**Awọn ti nwọn lọ ṣe ayewo ofin na ni Ọgbẹni E. I. G. Uasworth t i o j ẹ Attorney General fun ilẹ Nigeria, O l o y e Rotimi Willinms Q C, Attorney General fun agbegbe Iwọ-Orun ilẹ Nigeria. Sir Harold Dencan. ọkan ninu** awọn Amọfin fun ẹgbẹ British Council, ati Ọgbẹni M. O Ajegbo ti o jẹ Attorney General fun agbegbe Ila-Orun ilẹ Nigeria.


MADE IN NIGERIA

WỌ FUN IGBADUN

S.O.K

ORIṢI MẸTA

SINGILẸTI

ELIZABETH MADE IN NIGERIA

S.O.K MADE IN NIGERIA

Kamson MADE IN NIGERIA

MANUFACTURERS:

Oriwu Commercial Agency Ltd.,

64, IDOLUWO STREET

LAGOS.

Phone 21564

SOLE DISTRIBUTORS:

Lokoomal Bros.,

LAGOS IBADAN KANO

Ambrose Asomugha

PLOT G2, SABONGARI,

ZARIA.


# Hogan Bassey Njijadu Lati Gboye Re Pada



**LOS ANGELES A gbọ irohin wipe n i gẹrẹ ti Hogan Bassey pada de ilu Amẹrika lati lọ gba oye Abẹṣẹ kun bi ojo rẹ wa le, ko fi akoko kan jafara, firi-firi lo bẹrẹ si danrawo.**

**Gẹrẹ ti o de ọhun ni on pẹlu ọkunrin kan ti o lara ba danra wo, ẹniti orukọ rẹ njẹ Joe Recerra, a si gbọ pe Hogan Bassey fi ṣe mo mulanu, ni Olympic Auditorium.**

Tessey sọ wipe bi a ko ba ri dasi ija on ti ọte yi da on loju ju ọṣẹ lọ. Nibiti Ọgbẹni Bassey g b e udanrawo, ni ọkunrin kan, ẹniti Bassey ti lu bi olokugbẹ ni akoko kan tun gboju-gbaiya wa pe Bassey nija sugbọn a gbọ pe Bassey fi oju rẹ ri mabo. Ija yi fun gbogbo enia ni ireti wipe yio yege ninu ija rẹ pẹlu Moore

BASSEY NGBARADI !

## AWỌN OBINRIN NIGERIA KỌWE SI ỌBA GẸSI

Awon agbajo ẹgbẹ obinrin ilẹ Nigeria ti a npe ni (The Federation of Nigerian W o m e m Organisation) tẹ waya abẹomi ranṣẹ si Alaiyeluwa Queen Elisabeth keji ọba Gẹsi nipa ẹtu oloro ti awon Faranse fẹ yin wipe ki o jọwọ ba won kilọ fun won ki nwon maṣe ju etu na nitori awon ọkọ won wa nibe ọmọ won wa nibẹ, awon ẹbi won gbogbo la wa leti ibiti nwon nlọ ju etu na.

Nitoripe ohun ti Faranse lero wipe o jẹ nkan ere fun awon, iku lo jẹ fun awa nilẹ Nigeria. Orişirişi ẹgbẹ awon obinrin ti o mbe nilu oyinbo ni nwon ranṣe si pelu. Bi Conservative Party, Trades Union Congress, Labour Party.

Bakanna ni awon ẹgbe obinrin tilu Ibadan gbero lati lo ese gigun nipa etu oloro ti nwon fe danwo yi.

# Iyawo Adajo Agba Gboye M.B.E. Nilu Oyinbo



Awon meji ti a nwo ninu aworan y i ni iyawo Adajo agba. Iyafin Ademola lo duro lowo osi ati Iyafin Abayomi lo duro lowo otun. O nfi ami (Medal) oye M. B. E. ti iya Oba obinrin gbe fun u han Iyafin Abayomi.

Awon obinrin olola meiji nwonyi ti lo silu Oyinbo fun ipade egbe alanu awon olokunrun enia (British Red Cross Society).

## OMO OLOWOGBOWO KAN GBA OYE DOKITA NI AMERIKA

U.S.A. Okan ninu awon omo adugbo Olowogbowo nilu Eko, ti o lo fun ilosiwaju eko nile Amerika ti oruko re nje Babatunde Williams Ph. D, o si je okan ninu awon ebi Alhaji Issa Williams, ni a gbo wipe o gba oye Dokita nilu Amerika.

Asoro ailudi lo pa Ele-mpe isiwaju ti o wipe, igba wuwo ju awo lo. Oye Dokita ti Babatunde Williams gba na, ko nse Dokita ti Isegun bikoşe ti imo eko iwe.

Dr. Tunde Williams ti a wi yi je omo odun merindilogbon, ninu odun 1949 lo ba oko lo si Amerika fun ilosiwaju eko, on si ni igbakeji Professor ni ile eko University ni Northern Illinois Dekalb.

A tun gbo wipe, Dr. Babatunde Williams ngbero lati pada wa sile boya ninu osu August, şugbon yio koko ya ni ilu Oyinbo Gesi ki o to ma bo nile.

## EDEKOYEDE BE SILE LARIN N.C.N.C. IBADAN

BENIN. Agbo wipe awon omo egbe ti igboro ilu Ibadan ni ikunsinu si ara won. Ninu ipade kan ti awon lo se nilu Benin, ibe ni odekoyede na ti bere.

Mojidi omo salami Ayeye ni a gbo wipe o nse Alaga a w o n omo egbe N.C.N.C. ti a daduro kuro lenu ise, eni kan si wa ti o mba Mojidi na du ipo Alaga bi oti eni k e j i n a b a w o l e dandan ni ki nwon yo Mojidi kuro ni Alaga.

Agbo pe igbimo ti nwon se ni ojo sunday ni Benin, ija ni won fi tuka. Awon to je asiwaju ninu egbe wa lo ba ara won pade ninu ile agbawo won nwon si mba ara won jirobo nipa ipade yi, T.O.S. wa nibe Akin wa nibe pelu.

Ipinnu ti nwon se ni wipe, bi nwon ba fi yo Mojidi kuro ni Alaga egbe N.C.N.C., eni ti nwon ma jijadu fun lati fi se Alaga ni T.O.S. tabi Ade. gegebi nwon ti fi ija tuka ni gboro ilu Benin, boya nwon o tun pe ipade sibomiran.

## Why N.C.N.C. Is Worried

(Continue from last week)

The coming General and Regional elections give him more fever than ever.

For the interest of the public those who still hange in the NCNC study carefully the position of things and get out of the sinking boat to a life ship of boon voyage to the Salvation of our beloved Country. I will mention few of those things that worried Dr. Azikiwe.

(1) That Dr. Azikiwe's ambtion to lead Nigeria has met with entire failure when he was an Orator and a Director.

(2) That he lost his hope on every political success when on his rifth and left he could not see men like Dr. Kingsley Mbadiwe, Prof. Eyo Ita, Hon E. O Eyo, Dr. Hon Awduche Hon Sam Ikoku and many others who are men of will and Deeds. They all left the NCNC when democr cy was a sold to autorate

3 The NCNC in the Eastern region has become hopeles when, in a region which wa their strong hold now divided into four major political parties. region which formaly has no opposition benches is now bean opposed by those men of good will.

4 The NCNC position in the Western Region is growing from bad to worse.

(5) The NCNC cannot boast of any supporters in the Northern region. The NEPU who is alliance with them has no room in that Region.

(6) The headache in the NCNC is the 14 points Memorandum submitted to the pubic by the Action Group. The points contained only Facts and nothing.

## Oyin Ta Enia Pa

LOKOJA. A gbo irohin wipe oyin ta okunrin kan ti o nta tarare olorun didun ti oruko re nje Usman Dantata, ni atapa lojuona ni iwon ibuso meta sila Ilokoja.

Nwon ni okunrin na pelu aburo re okunrin ni nwon jijo nlo loju ona nigbati nwon de ibi awon oyin na gbe wa ni nwon dabo Usman nikan, nwon bo lati ori de ese, ti nwon si ta tai to fi subu lule, to si ku sibe.

Awon oyin na ko fowo kan aburo re okunrin, Abudu Danbata ti o tele lehin. Nwon ti gbe oku re lo sile Iwosan fun ayewo lati mo ohun to se'ku pa okunrin na.

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFE LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL XI. NO. 635. SATURDAY AUG. 1 - AUG. 7, 1959


# Eyi To Ironu fun Eniti O M'oye

Giri ṣolẹ lọjọ Satide nigbati adajọ agba, Ọgbẹni G. B. A Coker ṣa konko ẹwọn ọdun mẹrin-din-logọta mọ awọn ole ti o lọ ji ẹru aṣọ ko ni Bode Eko (Costums). Onidajọ agba na ṣ'anu awọn ogboju ole to nja lọsan-gangan na nipa wipe ki nwọn ṣe ẹwọn na ni aṣepọ eyiti o mu ki bi ogun ọdun dinku ninu ijiya wọn.

Awọn ọdaran na ni a to si isalẹ wọnyi pẹlu ọdun ti olukuluku wọn yio ṣe ninu ọgba ẹwọn

Edmond Wiwo, ọdun mẹrin fun igbimọpọ lati ṣe iṣẹ aidara ati ọdun mẹfa fun ole jija. Rasaki Kafaru bakanna pẹlu Wiwo. Ọlabọde Sanya, ọdun mẹrin fun igbimọpọ ati ọdun meje fun ole jija.

(Ki a ma gbagbe pe Sanya nṣe ẹwọn ọdun mẹfa-abọ lọwọ fun ole to ja ni Bọde ṣiwaju eyi). Rahimi Adebisi, ọdun mẹrin fun igbimọpọ ati ọdun mefa fun ole jija. Mu itala Alao ọdun mẹfa fun gbigba ẹru ole dani. Sikiru Abiọla, ọdun mẹrin fun igbimọpọ ati ọdun mẹrin fun gbigba ẹru ole. Obinrin kan to wa larin ọdaran wọnyi ni Ashiatu Esu ni adajọ fi si ẹwọn oṣu mejila fun gbigba ẹru ole dani.

Bi Adajọ ti ṣe idajọ le wọn lori tan ni Edmond Wiwo boju wo ọtun o wo osi, o si bu s'ẹkun, o mbẹ adajọ pẹlu ohun iwariri wipe, Oluwa mi, f'oju anu wo mi, ọmọ orukan ni mi, emi si ni baba awọn ọmọ wẹrẹ meje. Adajọ si fesi da lohun pe iyẹn ni iwọ iba kọfi s'ero pe o ni ọmọ wẹrẹ meje, ki o to lọ fọwọ si iṣẹ iru eyi.

Ẹnyin enia wa, ẹ fi eyi kọgbọn.


OMORELA

Is the ever-ready Way to get rapid relief from Cough, Cold, Fever and all Children ailments.



This is a well tried remedy
a Chemist Product.

Commercial Medicine STORES
LAGOS & IBADAN.


## Oba Kan Ku Sinu Salanga

SHAGAMU. Irohin kan wa wipe Ọba ilu kan, ni agbegbe ilu Shagamu, eniti o ti dagba to ẹni ọgorin odun, ti o si jẹ ọkan ninu awọn adajọ ninu kotu Ijoba ibilẹ, l'o ku sinu Ṣalanga ti agbara ojo ti wojo po sinu rẹ.

Nigbati ọba na fi ja sinu ṣalanga yi, ko si ẹniti o ṣoju rẹ ṣugbon nigbati nwon bẹrẹ si wa ọba na kiri, ni ẹnikan taju kan ti o ri bata ẹsẹ ọba na ti o fo soju omi inu Ṣalanga, ati apakan ẹwu ti oba na wọ fo soju omi inu Ṣalanga na nigbana ni nwon to mọ pe oba ti ja sinu Ṣalanga.

Pẹlupẹlu, nwọn ri oju apa ẹsẹ rẹ nibiti o gbe yọ tẹrẹ ki o to wa ja sinu Ṣalanga. Awon ara ile ọba na yọ oku rẹ jade, nwon si gbe lọ sile Alaisan lati wadi wo kini sababi ti o fa iku rẹ. Bi a ba ti tun gbọ nipa irohin ọba yi, ao ma yin si nyin leti.




AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.


## POSTS AND TELEGRAPHS DIVISION OF THE MINISTRY OF COMMICATIONS AND AVIATION INTRODUCES: ENVELOPES BEARING NIGERIAN 3D POSTAGE STAMP

The Posts and Telegraphs Division of the Ministry of Communications and Aviation announces the introduction of a new facility in its postal services.

It is the introduction of ENVELOPES bearing the reproduction of the normal Nigerian threepence postage stamp. The envelopes, 5 3/8 inches by 4 1/2 inches will be sold for 3 1/2d each and for use in the Internal post

They will be available on sale at all Post Offices throughout the Federation as from the 1st of August, 1959.

**A. M. MUIR**
Permanent Secretary
Ministry of Communications and Aviation

## ỌDUN ỌRUNMILA 20TH OGUN, 1959.

Ajọdun ọdun Ọrunmila ni ao ṣe ni agbara Ẹlẹda ni Ọjọ-bọ ọjọ ogun oṣu ogun, 1959, yika ibiti "Ijọ ti Ọrunmila yi wa ni ayika ile ti Oduwa pẹlu ilu ati ifon".

Ninu Ajọyọ wa ti ọduuni, ki a maṣe gbagbe, ki a fi sọ kan pe ni oṣu Opepe ọdunni yi ni orilẹ-ede wa yi, ni igun mẹrin yio wo ile Ibo ni ọjọ kanna lati yan awon ti yio gba "OMINIRA" fun wa. Nitorina, ki a bẹbẹ, ki Ẹlẹda o dari okan wa, ki a le yan "Oninutitẹ, ọlọkan tutu, enirere ati alakikanju awon aṣoju, ti yio le mu wa de "Ile Ileri" na. "OMINIRA" na niyi! yio si dara fun gbogbo wa aṣẹ.

Ẹku ọdun, ẹku iyedun, ọdun ọdunni ayabo aṣẹ.

Gbadebo Dosumu.

Olulana & Araba Ijọ ti (A) Ọrunmila Agbaiye.

## Gomina Agba Lo Sile Ghana



O to iwọn ọjọ mẹta ti a ti ngbọ irohin wipe Gomina Agba fẹ rin irin ajo lọ silẹ Ghana. Nisisiyi a ti gbọ pe Gomina agba tilẹ Nigeria Sir James Robertson, ti gunlẹ silẹ awọn Aganyin (Ghana). Ọgbẹni Lord Listowel lo si gba ni alejo. Ọjọ mẹrin pere ni a gbọ wipe nwọn fẹ lo nilẹ na.

## ẸRU TI ONIBODE GBA LỌWỌ ONIFAYAWỌ

EKO. Iwonyi ni awon ẹru ti awon Onibode gba silẹ lọwọ awon onifayawo. Nkan mẹtalelọgọta ni nwon gba silẹ ni Ebuti Eko, larin ibẹrẹ oṣu January si ipari oṣu June 1958.

Ni ẹsi, nkan marundilogoji ni awon Onibode gba sibẹ kuro lọwọ awon onifayawọ.

Iwon ọti (gallons) ti nwon gba kuro lọwọ onifayawo jẹ 282 Ni ọdun ẹsi, iwon meta pere ni nwon ri gba; ati ati iwon ọti wine meji ati abọ ni nwon ri gba lọdunni, nigbati o jẹ pe, a ko tilẹ ri nkan to jọ bẹ gba ra ra lọdun ẹsi.

Iye Siga ti a ri gba, bi a ba ka won ni ẹyọ kọkan, jẹ 23,973 ṣugbon lodun to kọja iye awon Siga ti a ri gba kuro lọwọ awọn onifayawọ 29,310 ni ọdun 1958.

Owo ti a ri kojọ gegẹbi owo ijiya lọdunni jẹ £671 - 12s. Ṣugbon iye owo ijiya ti ọdun to koja jẹ £264.

## ORO EDUN AWON NIA DUDU TI DE ODO FARANSE

LONDON. Sekiteri alaboju to awon ile ajeji ti mu oro edun awon ara ilu Nigeria lo siwaju Ijoba Faranse, nwon si ti fi abo fun Sir Lennox Boyd.

Ogbeni Fenner Brockway bere lowo Lennox Boyd kini itobin ti o gbo lati idale wa nipa wipe, ki Ijoba Gesi lo ri Ijoba Faranse nipa etu oloro ti nwon fe ju?

Lennox Boyd dahun pe, Gomina agba tile Nigeria ti so fun on nipa igbimo ti nwon se ninu osu February ninu eyiti olukuluku igbimo soro edun won jade nipa etu oloro ti awon Faranse fe ju sinu. okun yanrin Sahara ninu ile igbimo nla tilu Eko, mo si ti fi iwe ranse gegebi o ti wi si Ijoba Faranse, nko si ti ri esi gba nipa oro yi.

## AWON TO SEWE OWO, TI KO NI OTITE LUGBADI OFIN

KANO. A ri gbo wipe awon enia awonyi, Edwin Owele, Bassey Umoh, Simon Nwibari, James Akwaji, Agada Ogoja ati Joel Albi, ni nwon gba owo lowo awon enia ti nwon se iwe wipe nwon ri owo gba, sugbon won ko fi otite si (stamp).

Awon olopa ko awon enia na lo siwaju Alikali, o si pase pe ki eni kokan won lo san p o n u n mewa-mewa tabi bi nwon ko ba ri owo san, ki eni kokan won lo si ewon osu kokan.

## IFORUKỌ SILẸ FUN ILEWE ỌMỌDE YIO BẸRẸ

EKO. Ẹdẹgbata ni awon ọmọ wẹrẹ ti a gbọ pe, nwon o fi oruko silẹ lati bẹrẹ ilewe ni ọdun ti o mbọ 1960.

Ọjọ ti nwon o bẹrẹ si fi oruko awon omo wẹrẹ ti yio bere ile ẹkọ ni odun 1960 silẹ ni ipari oṣu August titi de ọjọ keji oṣu September 1959.

Aye meji lelogota ni yio si sile nibiti ao ti ma fi oruko awon omode ti yio bere ilewẹ sile. Nwon o se ikede awon aye na laipe.

Afe ki o ye nyin wipe, awon omo ti a bi ni odun 1954 tabi awon ti o sese nlo pe odun mefa ni ao gba si ilewe ni 1960.

Bi awọn obi ọmọ ko ba le yọ iwe ọjọ ibi ọmọ wọn jade, akọwe ti o mu iṣẹ na dani yio ṣe iwe ni iye ọdun ti o ro pe ọmọ na to ki awọn obi omo na si fi han pe ilu Eko ni omo na ngbe.



## Itan Awon Omoba Meje

(APA 3)

(Lati owo Arokin)

Bi Akanbi omo oba Orongun Illa ti nlo si ona Ile-Ife beni o pade Kure-kure kan, ti o wi fun u pe, lowo ebi mpa mi fun mi ni nkan je. Omoba na dahun pelu erin ati oyaya wipe ha! ore mi, ebi npa emi na, sunmo ihin ki a jo maa jowo-bowo.

O lowo bo apo e yo akasu eko meji ati obi adie meji, o mu okan fun Kure-kure, nwon si jijo jeun na. Nigbati nwon ya tan, o dide lati ma ba ona re lo, ni Kure-kure na ba pe e o wi fun pe, mo ti mo ibiti o gbe nlo, nitorina, ki o gba fila yi, bi o ba fi de ori, enikan ko ni ri o. Ki o si tun sora ma se gba olun kan lowo awon omoba na je. Bi nwon ni ki o fun eyan to ba wu o ninu won obikebire atapata ni ki o fe.

Nigbati Akanbi de odo Olofin o wi fun Akanbi pe, ni ni oru nigbati gbogbo enia ba ti sun tan ni awon omo on ma nlo si ode ijo ti on ko ni mimo kan nipa re. Nwon tun nlo ni ale yi bi o gba mo ibe, iwo yio fe okan ninu won, sugbon bi o ko ba mo ogo be o lori ni ola. O si mu Akanbi lo sodo awon omoba meje na, o wipe awon niyi.

Nigbati Akanbi de ibe ko to iseju marun ni o ti pirorọ pe on sun. Lojo na gan ni nwon fe se ere ola kan ni Aja'le. Nigbati o di agogo mejila oru ti owo pa, ti ese pa, olukuluku awon omoba meje nwonyi bere si gbaradi ni ero wipe Akanbi omo Orongun Illa ti sun lo.

Bi nwon ti nlo, eyi aburo sope ara niu oh, nje okunrin yi, ko ha ntele wa bi? Awon egbon re jara mo wipe, kalo, ko si ewu. Bi nwon ti nkoja lo labe igi faduka kan Akanbi ya die lara igi na, egbogbo won ta giri. Eyi aburo tun pe nko ti wi fun nyin pe okunrin yen ntele wa lehin; Sugbon nigbati nwon wo ra ra ra ti nwon ko ri, nwon dahun pe, e ma niso ko si ewu.

Eyi egbon lo siwaju, nigbati o de ibiti nwon ma koja si Aja'le, bi egbon ti koja tan beni Akanbi tete yara sokale tele lehin, nigbati nwon de odo Otefere kan lawon elegbe won ni aja ile mu oko wa pade won. Nibu oko ti egbon ni Akanbi wo sodi, Oloko na so pe, oko na nfa wuwo loni. Lose ti o mbo ao so ohun ti o sele ni aja'le lojum ... ma ka iwe irohin Eleti-Ofe. O kun fun irohin aladun.

## Olotu Ijoba Gesi



Eniti a nwo yi, Sir Harold Macmillan ti ise asiwaju awon oselu nilu Gesi, okan ninu awon omo lehin re lo dahun nigbati Denis Healey fi bere ninu igbimo kekere wipe, nje ijoba Gesi fi ara mo iwe ti ijoba ile Nigeria ko ranse si Ijoba Faranse? ni John Profumo ti o je okan ninu awon omo lehin Macmillan dahun pe, Rara! Ijoba Gesi ko fi ara mo nigbati nwon mu iwe na de nse ni a fi ranse be si Ijoba Faranse.

---

Plushes, Velvet, Velveteens, Damask & Building Materials.

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

## ASAYAN ORO

Omo mi, bi awon elese ba ntan o je iwo mase gba. Nitori okunrin wo lo nfe iye, ti o si nfe ojo pipe ki o le ma ri rere? Pa ahon re mo kuro ninu ibi ati ete re kuro ninu etan siso.

## Iyawo Salamotu Miringindin

MUSHIN. Nibi iyawo Salamotu Aniwura leti oja Mushin awon enia po bi omi, bi Yoruba ti po beni awon Hausa. Lemomu Jamiyu lo wa so yigi na.

Salamotu bere lowo Lemomu pe, gegebi eniti on fe yi, ko nse oko lo nfe on, bi kose pe on l'eniti o nfe oko na, nje o ha to ki on tun gba owo yigi lowo re bi?. Awon Alufa dahun pe, o to be. O so fun oko re pe, on yio gba Ponun marun lowo re.

Sugbon egbon oko iyawo na, ti o je okan ninu ebi Alasan Dantata dahun pe awa ri ikede re ninu iwe irohin, ati laiko mo wa ri, ti o si gba lati fe wa ogoji Ponun ni a fi so yigi na

Ibe ni okunrin kan gbe dide o ni on fi Ponun marun kun ogoji na. Laraba, obinrin Hausa kan ni on fi Ponun mewa kun owo yigi na Laifa orogun, owo yigi di Ponun marunle-logorun. Lehinti nwon so yigi tan, ni ojo Monday to lo yi, Salamotu ba oko re pada si Kano.

---

Kere o !

A ni orisirisi ogun German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO

BROTHERS

MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos

## ỌGBENI NJOKU ṢE ALAYE IṢẸ ỌKỌ



Laipẹ yi ni Ọgbẹni Raymond Amanse Njoku ọkan ninu awọn Minister ti ijọba apapọṣe ṣe alaye lori iṣẹ ọkọ niwaju awọn Oniwe Irohin.

Diẹ ninu awọn ohun ti o fa idi ipade na niyi: Awọn Ọlọkọ mẹdogun ni nwọn pe wipe ki nwon parapọ pẹlu ijọba Apapọṣe nigbati nwọn fẹ da ọkọ ti Nigeria silẹ.

Ninu awọn mẹdogun nwọnyi, ayafi Elder Dempster ati Palm-Line lo ṣe eto adehun ti Ijọba Apapọṣe gba.

## ENIA HA LE TILE AIYE WỌ INA LỌ SỌ'RUN BI?

Olotu,

Jowọ gba mi layé lati fesi si imọran ti Ọgbẹni J. A. O. Odupitan ṣe fun igbimọ Lagos Town Council wipe on damoran bi awọn enia ti npọ si bayi, ti awọn enia si oku pupọ, o yẹ ki nwon kọ pẹpẹ kan ni bi ti nwon o gbe ma sun awọn enia ti o ba ku.

Nitori owe Yoruba kan sọ bayi pe eyiti o wu mi ko wu ọ ni ti emi, emi ko fẹ ki ẹnikan da ina sun mi,,tabi enia ha le ti ile aiye wọ ina lọ si ọrun bi ? Mo si tanmọ wipe ọpọ awọn enia ni kọ fẹ ki a dana sun won pẹlu, nitori idi yi, mo lodi si imoran ti ọgbeni Odupitan mu wa fun Town Council na.

Ọmọ ti Noa bi.


## CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS :-

IKORODU TRADING COMPANY

20 & 28 Balogun Street Lagos


## AZIKIWE FẸ BẸRẸ ERỌ TELEVISION ILA-ORUN



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Dr. Nnamdi Azikiwe, nigbati o pada de ilu London lehin irin ajo rẹ lo si ile America so wipe on nireti lati bere eto gbogbo ti on ti se nipa ero Television ni agbegbe Ila orun ninu oṣu October, 1959.

## A Fese Kan Pa Meje

(Apa 8)

Afẹṣẹ pa meje sọ fun ọba wipe iṣẹ kanṣọṣọ ti o ku na ko ṣoro, ṣugbọn on fẹ o ki ọba kọ ile gbọrọ kan fun on ki o ma ni ferese, ki ni ilẹkun meji, ọkan niwaju ekeji lehin.

Nigbati nwọn pari ile na tan, Afẹṣẹ pa meje mu fere rẹ o nfọn kakiri inu igbo ti ẹranko na wa, o nwipe,

Oju tontoro fẹ toto,
Oju tontoro, fẹ toto.

Ariwo fere yi ko jẹki ẹranko na sun, o dide o nlepa onifere na bọ wa.

Gbara ti Afẹṣẹ pa meje ri ẹranko na, o sare wọ inu ile ti nwon kọ ẹranko na sare tele lẹhin. Nigbati o de ipekun o gba ohun jade, o si pa ilẹkun de, o tun sare wa si odi keji o tun pa ilẹkun ibẹ de.

Afẹṣẹ pa meje wa rin lọ si ọdọ ọba, o wipe, mo ti fa ẹranko na wọle, ranṣẹ lọ ki nwọn lọ yinbọn psa.

Inu gbogbo enia dun, nwọn ho fun ayọ, olowo mu owo wa, alaṣọ nmu aṣọ wa onidukia mu dukia wa.

Lọṣẹ ti o mbọ ao sọ nipa ti igbeyawo Afẹṣẹ pa meje ati gẹgẹbi o ti mu iyawo rẹ pada lọ sile.

## Ogunlogo Osiṣe Eedu Ni Nwọn Da Sile

ENUGU. Awọn enia bi ẹgbaa ninu awọn oṣiṣẹ to nwa eedu ghero lati da duro ku o lẹnu iṣẹ eedu wiwa, gbogbo wọn ni nwọn si ti ha ni iwe wipe nwọn ni lati da wọn duro.

A tun gbọ wipe lẹhinti nwọn ba da ẹgbaa enia nwọnyi duro tan nwon o tun da igba enia miran duro ninu awọn ti o nwa eedu.

Awọn Oyinbo Eleedu ati ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ to nwa eedu ba ara wọn ṣe adehun wipe nisisiyi ti eedu ko ta mọ, nwon o din iṣẹ eedu wiwa ku si igba mẹrin tabi mẹfa ni ọsẹ kan. Olukuluku awọn ti wọn daduro ni nwon ti fun ni owo rẹ pe.

Awon enia ti idaduro na kan ni awọn ti o ti nṣe iṣẹ eedu wiwa ṣiwaju ọdun 1936 ati awon ti o ṣeṣe wo iṣẹ lẹhin odun 1957.

Ọgbeni Chime ba awon Oyinbo Eleedu jiroro wipe iba je ohun ti yio sunwon bi nwon ba le wa ona miran ti a le lo eedu fun ki a ma ba da awon osiṣẹ nwonyi silẹ


## E MA KA

IWE IROHIN

## ELETI-OFE

LỌSỌSẸ

O KUN FUN

IROHIN ALADUN

FREE! GIFTS LUCKY WEEK 27th JULY to 1st AUG.

Bi iwọ ba ra ọja ninu ile itaja wa ninu ỌSẸ ORIRE yi (ti o pari loni ti o si nfi awọn iwe ... iwe to ti sanwo ti a fun ọ fun (ọja ti o ra) pamọ, o le s'orire lati ri ọkan gba ninu awọn ẹbun ti ao fi tọrẹ lọfẹ.

ẸBUN KINI



TELEFUNKEN
TELEVISION SET
Yiẹ ṣiṣe ẹdun kan lai ni iyọnu rara.

| ẸBUN KEJI | ẸBUN KETA |
| --- | --- |
| IWE OWO | ẸWU OBINRIN |
| Pọun mẹwa (£10 : 0 : 0) | ti o dara, ti o ba ọ mu. |
| Eyi ni wa fi ra ọja ti o to owo yi ni ile itaja wa. | ẸBUN KẸRIN |
| | Igo oti CHAMPAGNE mẹta ti o jẹ ojulowo |

Ni owuro ọjọ Monday ọjọ kẹta oṣu August ni ao yọ iwe mẹrin ninu awọn ti a ti fun yin fun ọja ti ẹ ra ti o jẹ Iwe ti o ṣ'orire, ni ọjọ keji ni ao tẹ sinu Iwe Irohin ojojumọ tilu Eko.

Bi o ba ti ra ọja pupọ si, ni wa fi ni aye ati ri Television kan gba lọfẹ lọwọ

BHOJSONS

OYINGBO, P O BOX 63, EBUTE-METTA

... ni tabi yio ye, ọwọ Ọlọrun ni iyoku wa. Ṣugbọn Padi obinrin na ti ku patapata, nwọn si ti sin oku rẹ ni ọjọ kanna nilu Gusau.

## Omo Oba Ilorin Salaisi

**ILỌRIN. Iyafin Titilọla Abudu Kadiri, ti o jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Ologbe Abudu Kadiri, Ọba Ilọrun ni a gbọ pe bi o ti bimọ tan bẹni o si ṣilẹ Ọlọrun wo.**

Titilọla bimọ sinu ile ile Alabiyamọ ni Ilọrin (Ilọrin Maternity Welfare Centre), o bi ọmọ na ni obinrin ni ọjọ Sunday ti o jẹ ọsẹ rere.

Nigbati Titi wa ni ọmọge. iṣẹ tẹwe-tẹwe lo nṣe ninu ile igbimọ Ijọba ibilẹ.

A ki awọn ọmọba pe nwọn ku ọfọ.

## OBOLE KI ALAGBEDE TO FORUKO IYA RE TA ORIRE

IBADAN. Okunrin Alagbede kan ti o fi oruko iya re ta orire, o si je ogorun poun.

Sugbon Ijoba Ibadan ko lati fun ni owo na, nitoripe iya ti nwon fi oruko re ta orire yi ti ku.

Omo iya na ti o nje Tiamiyu Olafoye lo pe ejo si kuto pe on lo fi oruko iya on ta orire ti o je ogorun poun.

Loya re so fun adajo pe, niwon igbati o je pe on lo fi oruko iyare ta, o ni eto lati gba ogorun poun na.

Sugbon Loya ti ijoba dahun pe, niwon igbati eni ti o ni etọ si owo na ti ku, a ko le ko owo fun elomiran.

## Ile Nigeria Ko Le Tosi Mo

**EKO. Oloye Okotie-Eboh sọ nilu Eko nigbati o pada de lati irin ajo rẹ lọ si Jerusalem wipe bi ilẹ Nigeria ko ba bọ si ọwọ ẹniti o jẹ oninakuna, ti ko si bo sọwọ ẹgbẹ buruku, ilẹ Nigeria ko le di onigbese mọ lailai.**

£15,000,000, iye owo ti Ijọba Gẹsi ya ilẹ Nigeria nwọn ni ki Ijọba apapọṣe fi tun ibiti o gbe udun u ṣe fun idagbasoke ilu, ṣugbọn on Okotie-Eboh ko le sọ, bawo ni yio ti pẹ to lati da owo yi pada.

Nwọn bere lọwọ rẹ pe awọn wo ni ẹgbẹ Dẹmọ ti o daruko ninu ọrọ rẹ? O dahun pe, awọn ẹgbẹ oṣelu miran wa ti ko fẹran ilu rẹ tabi awọn ti o jẹ alatako, bi iru awọn bẹ ba gba agba, awọn ti yio jade kuro nilu yio pọ.

## PADI OBINRIN PADE AGBAKO

ZARIA. Alufa obinrin kan ti o je ara Ijo Padi ti o ngba ẹbi fun awọn alaboyun ninu ile Alabiyamọ kan ti o mbe nilu Gusau lo nwa moto lọ lati Gusau, nigbati o sunmọ tosi ilu Funtua ni mọto rẹ sesi lọ fi ori so moto ẹlẹru nla kan lọjọ Saturday, 25th osu July 1959.

Omidan Frances Jafẹti, ti o mbe ninu mọto kanna pọ pẹlu Padi obinrin na, ni a gbọ wipe o fi ara sese pupọ ati pe o yi mbẹ ninu ile Alaisan yio ku

OVALTINE

Nfun Awon Omode Ni idunu ati alafia




O dara fun gbogbo ... Ovaltine je ohun ti o pe ... awon ... ati ... O ... lati ... ati ... wa yi ...

OWA314